ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL X V NO 915 LAGOS SATURDAY APRIL 4—APRIL 10 1964 KỌBỌ MEJI (.D)

LOYA OYINBO TI DE:

# Ejo Awolowo Ku Si Dede

EKO....Irohin n'la kan ti a gbọ loru ana ni ti ọgunagbongbo loya Oyinbo kan, Ọgbẹni Victor Durand, lọya Ọbabinrin ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre gba fun ẹjọ ko-te-mi-lọrun ti o wọlẹ yi lana pẹlu lọya ekeji rẹ, Ọgbẹni A. Killog lati wa ṣe ẹjọ na.

(Wo iyoku loju ewe kejọ)

# Oba Di Meji Ni Ilu Meka

JẸDA—Ko si ibiti ẹṣẹ ko si ni ile aiye, ilu Mẹka ti a tilẹ lero wipe awọn ara ilu ko ni wahala kan ti o ndi wọn lọwọ nipa ọrọ awọn oṣelu wọn ni a gbọ irohin wipe Ọba ti di meji ti o npaṣẹ lọwọ lọwọ fun awọn ara ilu nisisiyi.

A gbọ wipe lati nkan bi oṣu mẹsan ni awọn ijoye ilu Mẹka ti kọ ẹhin sọba wọn ti nwọn npe ni Ọba Saudi, ti nwọn ni ko fori itẹ silẹ tabi ki o fi aiku gbọ gbogbo agbara ati aṣẹ rẹ fun aburo rẹ ti nwọn npe ni Ọmọba Faisal.

A ko mọ nkan ti o fa idi ọrọ na ṣugbọn a gbọ wipe Ọba Mẹka, Saudi kọ fi aake kori lẹhinna awọn ara ilu sọ fun un wipe bẹ ni awọn fẹ ki o ṣe bi bẹkọ awọn ko ni de ọdọ rẹ mọ.

Awọn Olori awọn Janmọ Imale ilu Mẹka ni nwọn kọ kẹhin sọba na ki o to gba aṣẹ ti nwọn pa fun un ni alẹ ijọta wipe on ko gbogbo aṣẹ agbara ati Ọla Ọba on fun aburo on. Ọ a wa di meji ni ilu Mẹka nisisiyi.

## Kofoworola Iyawo Osho Jaiaisi

EKO— Ann ṣe wa lati gbọ iku iyawo Ọgbẹni Oladẹinde Ọshọ ti ile iṣẹ awọn Oyinbo elepo-mọto, ti orukọ rẹ njẹ Koforọla ti o jalaisi ni 12, Ch pel Street, ni iwaju Ṣọṣi Olowogbowo l'Eko ni ijẹsi.

A gbọ wipe arabinrin na ko ṣe amodi rara ki ọlọjọ to de ba ni irọlẹ ijẹta ni iti o gbe ti npaiṣẹ mọ lati fun awọn ọmọ rẹ ni onjẹ.

Ni ana ọjọ Jimọ ni nwọn si arabinrin na ighi ti nwọn ti ṣe isin ikẹhin fun un tan ni Ṣọṣi Ẹgja ni Oke-Arin. Oluwa ki o ba ọkọ rẹ wo awọn ọmọ ti o o fi silẹ.

# Onigbajamo Inalende Pidan Fun'Awon Alakori

IBADAN—Awọn egungun bi AIYELABỌLA, AJOFOJO ati AJOGBẸRU ni a ti ma ngbọ rohin wọn bi nwọn ti ma npa idan oriṣiriṣi ni ile Yoruba ri, a go mọ wipe awọn Yoruba ti o tun ni agbara abalaiye ti nwọn fi pamọ sibẹ aṣọ wa ati igbati awọn alakọri ariṣẹmaṣe, awọn oloṣelu-alufa kan lọ ba Ijẹbu Onigbajamọ (barber) kan ti orukọ rẹ njẹ Rasaki Ọshinlagun nibi ti o gbe nṣe iṣẹ rẹ ni [illegible] ni ijarun, ti nwọn na bi ejo-aijẹ [illegible] on, na si pidan meje ti ọdẹ pa fun awọn alakọri na.

Gẹgẹbi irohin ri a gbọ lati ọdọ akọwe onirohin wa, mọto kansiliọ ara Ibadan kan ni awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oṣelu oloro kan mu lọ ka Ọshinlagun mọle nibi iṣẹ oojọ wọ. Wara were awọn ti bẹrẹsi gba a leti. Nwọn ni ki o sọ wipe on ko ni ṣe ẹgbẹ oṣelu ti o ti nṣe mọ rara. Ṣugbati olukuluku enia wa, (Wo iyoku loju ewe keji)

## Mama 'Beka' Williams Olore Orun Re

EKO — Awọn egungun akewi kan wa ni orile Ijẹ ye ni ilẹ Yoruba ni aiye atijọ ti o jẹ wipe awọn ni orin pataki kan ti awọn ma nti yi awọn eniyan oninwa iwọ lọdọdun, iru orin na ni a le kọ fun Iya-afin Rebecca ('Bẹka') Adekunbi Williams (ọmọ Alufa L. O. Fadipẹ ti Ijọ Baptist ni Iṣẹrin ni Ibadan ri ) ti o jalaisi ni ọjọ Aje (Monday) ni ijẹrun.

Eni ọdun marundin ladọrin ni Iya-afin 'BẸKA' o bi je iyawo aiarede fun ologbe Ọgbẹni E. Williams ti ile ifowopamọ (Bank) ni Ebutegọri l'Eko. Ọmọ mẹfa ni ologbe na bi fun ọkọ rẹ ninu wọn ni Iya-afin Rasidat Onasanya Jaiaisi (ọga ilewe Ijọba fun awọn obinrin ni Idi-Aba, ni Abẹokuta; Ọgbẹni Akinpelu Williams ti o wa ni ile ọkọ ni ilu Oyinbo, Iya-afin Ọmọlade Williams, ti o nṣe nile iṣẹ awọn oloṣọwẹwẹ.

(Wo iyoku loju ewe kejọ)

# Onigbajamo Inalende Pidan

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ọshilagun paapa ba si ina fun wọn on na pe agbara ti o fi pamọ sabẹ aṣọ o ni ki gbogbo awọn alakọri na awọn oja awọn oṣelu ti nwọn nṣe janduku kakiri na ma na ara wọn, ki nwọn si ma gbara loti,

Lọgan nwọn ti bẹrẹsi na ara wọn ni koboko awọn mirun bẹrẹsi ya ara wọn lọbẹ, ẹjẹ nṣe yalo, o nṣe yolo.

Awọn kan ti gbetugbetu Ọshilagun ko mu ninu wọn ni nwọn fi agbara gbe Ọshilagun ju sinu moto ti nwọn gbe wa Nwọn ru lọ sinu buka kan ni ọja Dugbẹ nibiti nwọn gbe fọ "ṢOKO" fun un. Nibiti nwọn gbe ti ade Ẹgbẹni Onigbajamọ yi lakun ni a di afẹfẹ ategun mọ wọn lọwọ.

Awọn ti nwọn gbogbẹ ninu awọn arisẹmaṣe na wa ni ile alaisan ni Adeoyọ nibiti nwọn gbe ti ntọju wọn lọwọ nisisiyi.

## Egbe Alakuko Pade Agbako

IBADAN — Awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (NCNC) pade agbako ni Ẹlẹta leti Idiaro ni ijẹta nigbati awọn janduku sa awọn mẹrif kan, awọn Jimọ Akanji, Wahabi Abinumọle ati Lasisi Adedeji.

A gbọ wipe Idi-Ayunrẹ ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti mbọ nibiti nwọn gbe lọ duro fun ọkan ninu wọn t' ọlọpa ti mọle ki awọn janduku yi to da mọto wọn duro, ti nwọn bẹrẹsi pe wọn nija.

A gbọ wipe nwọn fi ada dara lọjọ na; awọn ọlọpa ni awọn si nwa nkan ti o fa idi ija awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu na.

## Nigerian In Britain Industrial Relations

LONDON — A study course in Britain for a senior Nigerian Union official is proving a "most valuable experience" - and nothing has interested him more than the month he is now spending on attachment with the Ministry of Labour Central Office for Wales.

He is Mr. R.A. Lawal of Kaduna, who is Assistant General Secretary of the Northern Nigeria Civil Servant Union. With him on his thirteen-weeks visit to Britain, sponsored by the Department of Technical Co-operation, are seventeen other overseas union officials.

"The value of the course lies in the fact that it covers the completed field of industrial relations, including the structure and functions of trade unions personnel management, wages staff training and industrial rehabilitation; Mr Lawal told our Corporations yesterday Tuesday.

Since his arrival in Britain on January 20 Mr. Lawal has attended lecture courses at the London Headquarters of the Ministry of Labour and of trades Union Congress. In Cardiff he has had discussions with labour and personnel officers in both private and public enterprises. In his more specialised field as a member of the Staff Side of the Whitles Council Mr. Lawal spent an afternoon discussing common problems with a British member a senior officer of the Ministry of Labour.



Aworan yi niti awon Arabinrin meta ti nwon pon omita

Plushes, Velvet Velveteens, Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

Okunowo Brothers

63 Massey Street, (Faji Market).

LAGOS, NIGERIA.

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE ti o kun fun irohin aladun losose.

# Isele Nla Pa Won Ni Amerika

ANCARAGE (ALASKA)— Ni owurọ ijẹsan t'se ojo Jimọ mimọ (Good Friday) ni iṣẹlẹ nla kan ṣẹ ni ilu kan ti nwọn npe ni Anchorage ni agbegbe Alaska, o si ṣe ẹpọlọpọ ẹmi lofo pẹlu awọn ile pelu.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa iṣẹlẹ na, a gbọ wipe awọn akọwe alatẹgun ti ilu Japan kọ ṣe ikilọ fun awọn ara ilu Amẹrika wipe atẹgun nla kan fẹ fẹ ti yio mu iṣẹlẹ nla kan lọwọ, nitorina ki gbogbo enia ṣọra.

Ọjọ keji ni iṣẹlẹ na ṣẹ nitotọ, o ju ẹgbẹrun enia lọ ti iṣẹlẹ na pa. awọn enia ti alapa ogri bo mọlẹ ko ni ye.

Gomina ilu Alaska, Ogbẹni William Egan ni ọkẹ aimoye owo ni nkan ti atẹgun iṣẹlẹ na baje fun wọn. Nwọn si wa ilẹnu nwọn nko awọn oku enia kuro ninu ilu na.

# Awen Ti Nwon Nro ibon F'ole

PARIS— Ọwọ awọn ọlọpa Faranse tẹ awọn alagbẹdẹ kan nibiti nwọn gbe ti rọ ibọn fun awọn ọlọṣa ninu igbo. Orukọ awọn alagbẹde Jamani meji na ni Herman Gebbert ati Karl Weschet.

Awọn ọlọpa Faranse ti o mu wọn ni ọgbọn awọn alagbẹde na pọ tobẹge ti o fi je wipe o si oni ti nwọn kọ le gba fi rọ ibọn rifọfa kinikinni bi gege ikọwe, ti o ba ri awọn ibọn na o ko ni ni mọ wipe nwọn le ṣe enia ni ijamba rara.

Nwọn ni bi awọn alagbẹde na ti rọ wọn tan ni awọn ... ara wọn, awọn mẹta ti ... nje Brahjia Gush F Fernand Fontan ati Angus Guenezu ti mba wọn wa awọn ọlọṣa ti nwọn ... awọn ibọn na ni ikoko lati ri nka lo nigbati nwọn ba fẹ fọ ile.

# Eleti - Ofe Daraba

# Awon Olopa Mu Oloye Ti Nwon Ri Ori Enia Nile Re

Port Harcourt—Gbogbo awọn ara abule ni Biara ni Ogoni leti Pọta ni nwọn sa fi abule wọn sile lọjọ ti nwọn fi rubọ si iledi kan ni ilu Ibo.

Ni ojiji ni awọn ọlọpa sare wọ inu abule na lọjọ ti nwọn wa tu iledi joye ni wọn nigbati wọn ngbọ lẹmọlemọ wipe nwọn fi enia rubọ nibẹ.

Gbara ti awọn Ọlọpa na ti wọ abule na ni baba ijoye na ti kilọ fun wọn wipe ki nwọn ma wọ iledi na nitoripe ẹmkẹni ko gbọdọ fọwọ kan awọn imalẹ ti nwọn nibẹ o ni ẹnikẹni ti o ba fọwọ kan wọn gbẹrọ.

Baba Oloye na ni on ni olori aborisa ti o mbọ wọn sugbọn on pẹlu ori awọn enia mẹta ti nwọn pa fi bọ awọn oris na ni awọn ọlọpa ko lọ si tesan awọn ọlọpa ni Pọta ni ijẹta.



# ELETI-OFẸ

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos; "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV, NO 915 SATURDAY April 4—April 10 1964.


## ORO OLOTU:

# Kini Mba Yin Leru?

Awọn agbalagba ni iwa ọmọ ni o ma nkọ ọmọ ṣe ogun okigbẹ; ko ye awa oniwe irohin Elet-Ẹfẹ si nkan ti o mba awọn alakoso Ijọba Apapọṣe lẹru l'Eko ti nwọn fi nṣọ fun awọn oga Ọlọpa nigbagbogbo wipe ki nwọn ṣe ofin ki ẹnikẹni maṣe ipade ode gbangba:

A ṣe akiyesi wipe o to ọdun meji gbako nisisiyi ti awọn ara ilu ko ti ni anfani lati ṣe ipade lode gbangba mọ. Ko ye wa si nkan ti o fa a; a gbọ ti Ipinlẹ Iwọ Orun ti awọn alakoso Ijọba ko roju raye, ewo ni ti awọn ara Eko?

Ninu iwe ofin Ijọba ti gbogbo wa fọwọ si, nkan ti o wa nibẹ gẹgẹbi adehun ni wipe anfani a wa fun awọn ara ilu lati rin irin ẹsẹ wọn nibikibi, nwọn a si tun ṣe ẹsin kẹsin ti o ba wu wọn, ẹnikẹni ko si ni idi ẹnikan lọwọ lati sin oriṣa tabi imọlẹ ti o ba wu u.

Kini o wa mba Ijọba lẹru ti nwọn fi nṣe ofin nigba gbogbo wipe ki ẹnikan maṣe se ipade tabi ki nwọn to lọwọ ọwọ ni Ita-gbangba. Ọr... na ko ye wa si, o yẹ ki olukuluku enia rin irin ẹsẹ rẹ.

# Eleti-Ofe D'araba

# Iwe Si Olotu

## "YORUBA RONU"!

# Yoruba Ni Awon Ko Ronu . .

IBADAN— Ere ola kan ti Ọgbẹni Ijebu elere kan ti a npe ni Hubert Ogunde ṣẹṣẹ gbe jade ti o sọ orukọ ere na ni YORUBA RONU ni a gbọ wipe o ti di egungun ti o ha awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lọrun ni Ibadan nibi ti o fi di nkan ti nwọn ni lati fi ofin alabẹ-kenkele kan gba a nidi ninu ọsẹ yi.

Gẹgẹbi iwe ofin alabẹ-kenkele ti Gomina Ipinlẹ na fọwọ si ni irọlẹ ijẹta, nwọn ni awọn fi aṣẹ ki Ọgbẹni Ogunde elere YORUBA RONU ti o ṣẹṣẹ bẹrẹ lati ma ṣe ere na kiri ki o yara mọsa, ki o ko igba ere na sile nitoripe o le da ruke rudo silẹ larin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Boya ẹ le bere wipe kinise ti Ijọba ṣe tako ere aladun ti o dun rinrin bayi, Ọgbẹni Oguude ti bẹrẹ ere ṣiṣe lati nkan bi ọdu mejidinlogun sẹhin, tẹletẹlẹ iṣẹ Ọlọpa ni Ọgbẹni Ogunde nṣe.

Ṣe awọn ti nwọn nsere ta le ronu pupọ ko ba ṣe Oyinbo alawọ funfun ni tabi enia dudu; a ro wipe nibi ijinlẹ inu riro yi ni o mu ki Ogunde ro gbogbo nkan ti o ṣẹlẹ si awọn ọmọ Yoruba ni Ipinle Iwọ Orun lati bi ọdun mẹta sẹhin, ni o fi gbe ere ati orin ti o pe ni YORUBA RONU jade.

Bi ẹ ko ba ti lọ wo ere na, nkan ti a ri wipe wọn se ninu ere na nyi:

Ogunde ni nigba kan ni ilẹ Yoruba Ọba kan jẹ ti orukọ rẹ njẹ Fiwajoye, aiye rẹ si rọ lẹru tọmọ lọrun; gbogbo ara ilu ni nwọn nta, ti nwọn nra; ngowo nwọn si njere, Ọba Fiwajoye wa ni igbakeji kan ti orukọ rẹ njẹ EKEJI OYE Ọpa ọba ti Fiwajoye fi nto gbogbo eto ilu dede ni ỌPA ODUDUWA.

Lọdọ awọn joye ati Ekeji—Oye ni Ọba Fiwajoye ni ki nwọn ma toju opa aṣiri yi si. Iya

(Wo yoku loju ewe karun)


DAGENITE

BATTERIES

give you a longer run for your money!




★ longer life
★ improved electrical efficiency
★ dry charged

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

" YORUBA RONU "

# Yoruba Ni Awon Ko Ronu ..

( O bere loju ewe kerin )

gbogbo awon omo Yoruba ti oruko re nje Yeye-Oloye ni o fi opa yi da Oba a lola sugbon inu Ekeji—oye ko dun si i, o si nwa ona bi yio tise be aiye oba Fiwajoye je.

Ote ati tembelekun wa bere, Ekeji—Oye wa gbo gun ti Oba yi labe-e; o wa ona o lo gbe OPA ODUDUWA ti Oba fi nmu ilu dun lo fun awon ota Oba ti nwon wa ni ipinle miran ti oruko Obabinrin ilu na nje YEYE ILOBA.

Teletele Yeye Iloba ti nwon ona ti yio gba mu awon Yoruba leru, o si ti se ileri wipe on ko ko owo iyekiye lati fi fun enikeni ti o ba le ta opa na fun on.

Nigbati owo Yeye Iloba ti te opa na inu re dun, o si fi o o da Ekeji— e ti o wa ta awon enia re Yoruba fun on lola; Yeye-Iloba wa beresi mu mu awon Yoruba leru ni oko kan bi eni mu eran sin,

gbogbo nkan ko wa lo deede mo fun awon Yoruba.

Nwon gbin agbado ko gbo nwon gbin eree ko so, nwon gbin isu ko ta; awon ti nwon nsowo ko jere, gbogbo nkan wa di rudurudu nilu,

Awon Yoruba ti nwon ti nmu enia sin, ti nwon t je ENI—A—JI—TANA WO wa di eniti a ki ri mo. Nitoto nigbati Oba Fiwajoye ko lo tefa si oro na, Babalawo so asotele fun un gbogbo nkan ti yio sele si awon enia re sugbon Oba ko tete rubo nla ti nwon yan fun un Iya si nje awon Yoruba ni a je dob..

Eyi ni o mu Ogbeni Ogunde gbe orin YORUBA RONU jade pelu ere re ti awon alakoso Ijoba Ipinle Iwo oorun fi fi ofin le e wipe nitoripe oloye ni oro mba wi, ere na le da Ijoba awon ru mo awon lowo.

# E Ka Oro Olotu

## ti o kun Oro isiri

(loju ewe keri..)

# Ejo Babalosa Pa Oyilidi Ni Awka

AWKA— Aransi ni eleyi ni tabi kilo jo ? O o ejo ile orisa kan ti a gbo wipe o pa Obinrin ka , Oyilidi Dibua ara Awka loju orun ninu ile re ni o je ki a wi bayi.

A gbo wipe obinrin yi Oyilidi sese ko ile re na seti ile orisa awon ara Awaka ni, nwon ni babalosa si so fun wipe ki o fi ile na sile fun igba die ti awon yio fun igba die ti awon yio fi setutu fun un, nwon ni o ko jale.

Nwon ni ojo keta ki ijamba yi to se obinrin yi ni awon ara ilu ti nse akiyesi orisirisi awon ejo ti nwon nwo kiri ori iganna ile orisa na.

Loru ni 'okan wole to Oyilide iya onile tuntun yi ti o buje, o logun to o sugbon eru ti mba awon ara ilu ko jeki awon le ran an lowo, o si ku bamubamu.

## Dokita Wayo Lo Sewon Osu Mefa

PORT-HARCOURT— O be i kad Eye Nsa ti won Olopa ni o nse se dokita aigba we ... ti a gbo wipe Adajo Pota kan so sewon odun ... fun omolomo ti o wo ni awopa.

Adajo agba Ogbeni H. Bethuel ti nwon ro ejo na ni iwaju re ni on gbo gbo wipe nitoto ni o ba odomode kan Matilda James se oyun, sise oyun na ti nwon se oyun na lona buruku ni o pa omo omobinrin na.

Adajo ... kan ... nwon ape ... M nday Im kom ti ... mu re ... Nsa ... si eri ti o m ... na ju wipe ... omobinrin na lona.



# Eniti Olorun Ko Pa Enia Kole Pa

### Lati Ọwọ O. Oluwo

Itan mi na lọ bayi:- Nigba laijlai, Baba kan wa ninu ilu kan pẹlu iyawo rẹ bi ilu t ti bi ẹnikan ba bi ọmọ mẹta lẹkanṣoṣo (Ibẹta) aṣọ to ba wa lorun ọba ilu na ati ati awọn ohun meremere tijo ka fi ṣẹṣọ sara yio jẹ ti baba ibẹtẹ baba yi si jẹ agbẹ oko l'o nro.

Iyawo Baba yi wa ni oyun sinu baba yi si jẹ agbẹ (Farmer) o wa di ni o urọ ọjọ kan bi baba yi ti ji o wa di ni owurọ ọjọ kan bi baba yi ti ji o wa na tọtọ, (oyan) o ni aiye on ju ti ba ilu yi lo gbigbọ ti awọn ara ilu yi gbọ bẹni wọn fi ori le ile ni, wọn ni lagbaja ni aiye ti on ju ti ọba ilu yi lọ Kabiyesi Ọba ni kinnla lẹsẹkẹsẹ ọba si ran ni lọ si ile baba yi pe ki o wa ro ti ẹnu rẹ ki on gbọ sagbọn wọn ko ba baba na n le o ti lọ si oko.

Bi baba yi ti nlọ si oko o fi ẹsẹ kọ bẹn ẹkanna isa baba na nṣe ẹiẹ wowo, bẹni baba yi sọpe 'on ṣẹdun bọ epo ṣubu lu oyin o fi ori le ọna oko rẹ bi ti o de oko rẹ o si de takute si oko rẹ. Takute yẹn lo kọkọ lọ wo bi o ti de ibi ti takute wa kori takute owo hin-wo ohun ko ri takute na:

Bi o ti wo ẹgbẹ kan igbe ẹni o ri takute rẹ pẹlu an ọya, baba yi tun sọpe on ṣẹṣẹ ndun bọ epo ṣubu lu oyin' ẹnu ti o gbe soke bayi oyin lo kan si nu (Honey).

Nigbana ni Baba yi wa bẹrẹ si roko rẹ lọ, bi ti o nro oko rẹ lọ, bẹni o kan ẹyin aparo, Baba yi wa sọpe aiye on dun ju aiye ọba lọ, Baba yi bẹrẹ iṣẹ rẹ o nro oko kaukau-kau ko pe o kan iho Okete kan kikan ti o kan iho okete yi o bẹrẹ si gbẹ ! o gbẹ! o gbẹ !!! titi o fi kan Okete na, Okete meji lo pa ninu iho na inu Baba yi tun dun bakanna o tun sọ gẹgẹ bi o ti ma nsọ tẹlẹ ri.

Nigbana lowa mura lati pada si ile re bi o ti nlọ si ile rẹ bẹni o gbọ dundun ẹiyẹ kan ti ndun bayi o ṣorire! o ṣ rire!! o ṣorire O ẹ eti silẹ nigbọ dundun ẹiyẹ yi ? o jẹ iyalẹnu fun gidigidi nitoripe ko gbọ iru rẹ ri, bi o ti n'ọ bẹni ẹiyẹ yi ntẹle nigbati o de ẹnu ọna odi ilu ni ẹiyẹ yi to pada lẹhin rẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT

IKORODU TRADING COMPANY

20 & 28 Balogun Street, Lagos

*YOUR SPECIALIST FOR ALL*

BUILDING MATERIALS

**BROSSETTE (NIGERIA) LTD.**

WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA

*At your service*

- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS

**E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin**

**ELETI—OFE**

**ti okun fun irohin aladun lọsọse.**

# Britain's New Unified Ministry Of Defence

LONDON — Britain's ew unified Ministry of Defenc began work from its new headquaters in London on Wednesday.

The new Ministry will absorb the existing Service Departments - the Admirablty, the War Office and and the Air Ministry. It will have a Secretary of State for Defence at its head, assisted by three Ministers of Defence (Army, Navy and Air Force).

It has een established under new legislation and is intended to strengthen he central organisation for Britain's defence. The reoganisation will improve the cenrral contrel of defence policy, the arrangments for formulating weapons requirements, and the means of controlling research and development. It also aims of greater efficie cy and economy by creating the opportunity for a common defence approach.

The new Ministry, with an annual bedget of nearly £2,000 million, will have responsibility for 400,000 Services personnel and as many civilians.

With its creation, the ministerial appointment of First Lord of the Admiralty, Secretary of State for War, and Secretary of State for Air will be abolished.

The changes do not affect the Armed Services which will pr serve their seperat identities as the Royal Navy, the Army, and the Ropal Air Force.

Although the Minisrry of Aviation is not brought within the new unfied Ministry, there will be the closest 'co-operation. The Minister of Aviation and many of his chief advisers will be located in the Minisiry of Defence building.

## Tanganyika Studies Poultry Husband In England

**Mr. Simon J. Ikolo from Ndala Parish Tabora. Tanganyika examines a laying hen in the National Institute of Poultry Husbandry at the Harper Adams Agricultural Collegn in Shrops hire western England Mr Ikolo is one of many Commonwealth students who are taking a wide variety of courses at the college.**

## Carringt n For Rangoon

LONDON — Lord Carrington the Cabinet Minister who will lead the British delegation to the 10th anniversary meeting of the S.E.A.T.O. Ministerial Council in Manila this month, is also to visit Rangoon, Kaula Lumpur and Saigon.

The Foreign Office Spokesman announced yesterday, that the Lord Carrington, who is Minister without Portfolio in Sir Alec Douglas-Home's Goverament, will take advantage of his presence in South East Asia to make official visits to these other capitals.

Lord Carrington will leave London on April 6 and hold talks with government leaders at Rangoon and Kaula Lumpur before attending the S.E.A.T.O meeting. He will visit Saigon on the way back to London

## M butu's First Visit To Britain

LOND N Ge er J seph M he Army Comm he Congo s expec vs B tain ards the of April. ccp d ano cemet from offic s ce Le poldville.

Duri his stay as guest f he B sh G ver me t fr pril 1 - he Ge er w v s te m ry sta sh e s t il be h s fi st v si to Britis .

# Eleti - Ofe Daraba



ENMỌ WOLU;

## Awon Ibo Gba Reluwe Kan, Yoruba Renu

IBADAN— Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ tuntun ti awọn ṣẹṣẹ da sile ti fi si si ọrọ ti Dokita Okechukwu Ikejiani alaga ile iṣẹ Reluwe sọ fun awọn onịwe irohin wipe irọ ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ n mọ on wipe awọn Ibo nikan n i awọn fi ṣe olori olori ni gbogbo ibi ṣẹ reluwe.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni Dokita Ikejiani fi ẹtẹ silẹ o npa lapalapa Awọn ọmọ ẹgbẹ na da oruko ibi iṣẹ nianla ni ọgba Reluwe bị ọgbọn ọna nị Ebute-Mẹtta ti o jẹ wipe awọn Ibo ni nwọn ko sibe bam ubamu pẹlu owo kabi ika biti ti nwọn mbu lu rara wọn, ti nwọn nṣe yala yolo,

Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni ehin ẹnu ni Dokita Ikejiani nje ko ti ṣe alaye bi gbogbo na ti ri fun awọn ara ilu gbo.

---

## Bi Olorun Ko Pani

(O bẹrẹ i oju ewe kẹfa)

Ki a ma fa ọrẹ na gun lọ titi o wo ilẹ bi o ti nwo ilẹ fun nwọn jiṣọ fun pe, Ọba an ni de ile nigbati o lọ si oko tan o ni ki ẹ wa ti ẹ ba ti de. Oba a ti lero pe bi o ba ti de bibẹ ni nwọn yio bẹ lori bi baba ti de ẹdọ ọbe Ọba ti mura silẹ o wọ ẹwu ẹtu nla ṣanyan nla Bata oniyebiye Sokoto, Fila oruka Golu ọren lo ba ko fun ọkunrin yi.

---

YORUBA RONU

Ka ọrọ lorị YORUBA NI AWỌN KO RONU ni oju ewe kẹrin.

---

# Mama 'Beka Williams Olore Orun Re

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Lẹhin eleyi ni Ọgbẹnị Babajide Williams iyẹn na wa ni ilu Oyinbo) Ọgbẹni Akinyẹle Williams (ti o nsiṣẹ ni Ibadan) ati Adekunle Williams (ti on na wa ni ile ẹkọ ni London nisisịyi).

Ninu awọn ẹgbọn rẹ ni Ologbe iya-afin Luisa Ọmọtara Allen, Ologbe Dokịta Nat. O. Fadịpẹ, (tiṣa ilewe giga ti o jalaisi sị ilu Oyịnbo) Iya-afin Janet John) tị Alawode ni Ita Balogun l'Eko) pẹlu Adajọ-agba ni Oke Mapo ni Ibadan, Ọgbẹnị Louis Olubọdun Fadịpẹ.

Ẹsọ gbogbo awọn ọmọ Ijaiye, Ara badan pẹlu awọn ọmọ Eko ni awọn pe sibaṣiba si ibi isinku iya Oninure na ni Ṣọsi Bẹrẹfruru (St Paul's Breadfruit Church) l'Eko ni ọjọ ti nwọn gbe e lọ si itẹ.

A ki awọn ỌMỌLOKU, awọn ẹbi oku bi awọn Alawode, Allen ati Ogunmẹfun nwọn ku eschinde, Orin nla ni orin: IYA OLORE WỌLẸ NILẸ YI Ni JẸTA ti a kọ fun Ologbe na Adekunbi ọmọ Fadipẹ Bẹka" Ọrun re.

---

## Ejo Awolowo Ku Si Dede

(O bere loju ewe kinni)

A gbọ wịpe lọya na nlọ si Kotu ganran loni lati lọ fi orukọ silẹ fun iwe-aṣẹ lati le ṣe ẹjọ na. Gẹgẹbi ofin o ni lati gba iwe-aṣẹ lati ọdọ Ọga olori awọn adajọ-agba, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla.

A gbọ wipe ni ọjọ meje, ọjọ Jimọ ti mbọ ni awọn yịo bẹrẹsị ro ẹjọ-kotẹmi-lọrun na. Lọya kan ti o wa ni Ibadan, Ọgbẹni Olu Ayọọla ti tun fi awọn iwe kan ṣowọ si Kotu lati ṣe ịtọka si gbogbo ọna tị adajọ tị o ṣe idajọ wọn na fi kuna.

Awọn marun yoku ti nwọn tun sọ wipe ẹjọ ti Adajọ George Ṣhowẹm mọ da fun awọn ko tẹ awọn lọrun nịi Lateef Jakande, Simon Oyesilẹ, J. Oladiran Lawatson, S. T. Ọrẹdẹin ati Ayọ Akinsanya; gbogbo wọn ni awọn lọya wọn ti si duro ṣanṣan latị ro ẹjọ na ni ẹkunrẹrẹ.

Lati ọsẹ ti o lọ ni awọn ikọ ịlu igbimọ aṣofin ti nfi ẹnu kan ọrọ Oloye Ọbafẹmi Awolowọ na; ọkan nịnu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) nị ki nwọn da a silẹ kuro logba ẹwọn nitoripe lati ọjọ ti ti Awolọwọ mọle ni ịlu ko ti toro, o dabi ẹni wipe awọn Yoruba ko fẹ tẹle aṣiwaju miran ju Awolọwọ lọ:

Ṣugbọn ni ijẹta ni ọkan ninu awọn Hausa oṣelu ti o wa ninu ile igbimọ awọn aṣofi na ni on lodi si eto wipe kị nwọn da Oloye Awolọw silẹ nitoripe ẹṣẹ ti awọn Ọlọpa ni nwọn ṣe kiṣe nkan kekere rara


## AFRICAN SPECIAL

* Full tropicalisation and underbody protection plates
* Strong and comfortable suspension.
* Outstanding road holding.
* Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
* HIGH RESALE VALUE.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Phone 23370 Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box 467